# ELETI ỌFẸ

'A-[illegible]-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 893 LAGOS SATURDAY NOVEMBER 2—NOVEMBER 8 KOBỌ MEJI (2D) 1963

### Ogun Besile Nilu Dahomi:

# Awon Egun Ni 'E He o! Ao Gba Yini'

COTONOU (DAHOMEY)—Ogun adaja bẹ silẹ nilu awọn Dahọmi ni Ajaṣẹ ninu ọsẹ yi ti o fi di nkan ti Baalẹ alamojuto ilu wọn, Ọgbẹni Hubert Maga ni lati sa fi ile Ijọba ti o ngbe silẹ ki o lọ sabẹ abo lọdọ awọn sọja jagunjagun nigbati awọn oṣiṣẹ ilu rẹ ni a fi bi awọn ba bẹ ẹ lori bi o ba kọ lati ju iṣẹ alamojuto ijọba silẹ fun ẹlomiran

Rogbodiyan ti o bẹ silẹ ṣa kiṣe nkan kekere nitoripe ogunlọgọ awọn oṣiṣẹ ni nwọn rọ lọ sile Ọgbẹni Maga, alamojuto Ijọba ilu wọn na, nwọn ni ki o tu ile Igbimọ Aṣofin wọn ka ni kia-kia bi bẹkọ awọn yio pa idan meje ti ọdẹ npa fun un.

Bi awọn iṣi kan ti mba Ọgbẹni Maga finra ninu ile rẹ, ni awọn miran tun nle awọn minisita ilu Dahọmi kiri ninu ile wọn, ti nwọn nmu wọn ti mọle bi awọn arufin ti o jale.

Rogbodiyan ti ijẹta ni o le ju fun irọ nla kan ti awọn enia kan ngbe kiri wipe awọn ṣọja jagunjagun ilu na ti yinbọn pa Maga; awọn opurọ na ni nwọn ko fi pamọ rara nṣe ni nwọn ntan ara ilu jẹ

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## LAGOS RACE CLUB

The FOURTH DAY October Race Meeting will take place on Saturday 2nd November, 1963.

First Race at 3. 30 p.m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2 10/-, 2nd £1 10/-, and 3rd 10/-.

Also Two Silver Cups will be presented to the best dressed Ladies in national Costume and Western dress on the last d y of this meeting.

COME ONE COME ALL

Hon. SECRETARY
LAGOS RACE CLUB

### Aso Bosikona:

# Okotie-Eboh Bo Awon Loju Egungun, O Ni "Wayo" Wa

EKO — Minisita alamojuto eto inawo Ijọba gbogbogboo, Oloye Festus Okotie-Eboh bo awọn loju egungun fun awọn aṣoju awọn Ibo ti nwọn nra aṣọ aloku ("BỌSIKỌNA") lati ọdọ awọn Oyinbo ni ilu Oyinbo ti nwọn wa ba sọrọ wipe ki o jọwọ ba awọn rọ awọn alamojuto aṣẹ Ijọba ki nwọn ba awọn din owo-bode ku lori awọn aṣọ-aloku na. Nwọn ni owo-bode gọbọyi ti nwọn bu si awọn aṣọ-aloku na lori nle awọn oniṣowo Aba, Port-Harcourt Onitsha ati Enugu san lori iṣẹ aṣọ aloku na.

Awọn enia mẹrin ni awọn ikọ pataki ti awọn oniṣowo alaṣọ aloku na ran wa si Eko lati Ipinlẹ Ila Orun lati wa fọrọ wọrọ nipa iṣoro ti awọn alaṣọ aloku na nri lọdọ awọn akọwe ibode ni ebute ọkọ oju-omi ni Port—Harcourt nigbati nwon ba nta gbogbo awọn ẹru kọ aṣọ na yẹwo.

Nwọn si awọn fẹ ki minisita yi ba awọn bẹ awọn alakoso iṣẹ Ijọba ki awọn ba awọn din owo-bode si iye ti nsan ri.



Oloye F Okotie-Eboh

Oloye Okotie-Eboh ni on gbọ gbogbo nkan ti awọn ikọ na sọ patapata, o ni o wa Ijọba ki nwọn ara ilu ṣowo, ki nwọn jere ṣugbọn kiṣe ọna wayo ati jibiti ti nwọn kan ngba ṣowo yi O tun sọ alaye wipe nṣe ni awọn ẹnikan n'o aṣọ tuntun mọ aṣọ aloku ki nwọn ba ma san owo-bode fun Ijọba,

OWO IRIN ESE

# Adajo Agba Ni Ki Oloye Akintola Sanwo Fun Alihaji Adegbenro

EKO — Ọrọ Kotu, to ! to ! to! to ! Ninu ọsẹ yi ni Olori awọn adajọ agba, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla ṣe idajọ ẹjọ "tani o ni lati san owo irin ẹsẹ fun ẹnikan" ti Alhaji Dauda S. Adegbenro, asiwaju awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) pe Oloye S.L, Akintọla, Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lori ẹjọ are kan ti nwọn fi igba kan da a nilu Oyinbo nipa pe tani o tọ si lati ṣe Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun na.



Alhaji D. S. Adegbenro

[illegible] ile adajọ agba ko- [illegible] ẹjọ giga Ipinlẹ Iwọ [illegible] ni Ibadan fi igba [illegible] Oloye Akintọla [illegible] pe ọna ti nwọn [illegible] ni Olotu Ipinlẹ [illegible] a ko tọna rara, [illegible] e dajọ na nigba- [illegible] ki Alhaji Adegbenro [illegible] dotalerugba ponun ([illegible]) owo irin ẹsẹ fun Oloye Akintọla.

Onirohin wa ni Alhaji Adegbenro ti san owo na fun Oloye Akintọla ki o to gbe ẹjọ rẹ lọ si kotu nla [illegible]lorun ti o ga julọ ti o wa ni ilu Oyinbo, nibẹ ni nwọn ti da Alhaji Adegbenro lare wipe on ni aga Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tọsi.

Lẹhin eyi ile ẹjọ giga ti Ọba Obinrin Gẹẹsi wa tun paṣẹ wipe ki Oloye Akintọla lọ san ọgọtadinlẹgbẹfa ponun pẹlu sile mẹjọ ati kobọ mẹta £1,(140.8s.3d) owo irin ẹsẹ fun un.

Ninu oṣu keji lọhun ni Alhaji Adegbenro tun pe Oloye Akintọla lẹjọ si Kotu ile ẹjọ-giga wipe ki ile ẹjọ na ṣe iṣiro gbogbo owo ti Oloye Akintọla yio san fun [illegible] Nigbati Loya Alhaji Adegbenro, Oloye Akin Olugbade gbe ọrọ

(Wo yoku ẹju ewe kẹjọ)


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

### Invitation To Tender

Contracts for the supply of Shorehandling Labour at Apapa and Customs Quays Lagos

The Nigerian Ports Authority invites tenders from Registered Dock Labour Contractors to supply with adeqate surpervision, experienced registered dock labour for the handling of cargo at Apapa and Customs Quays, Lagos, in respect of the following Contracts .

APAPA QUAY

Shorehandling
Contract No 1 – No. 1 Berth and Lighter Berth.
Contract No. 2 – Nos. 2 (including 2A) and 3 Berths.
Contract No. 3 – Nos. 4, 5 and 6 Berths.
Contract No. 4 – Nos. 7, 8 and 9 Berths.

Warehouse and Offloading Operations
Contract No. 5 – 'A', and 'C' Warehouses.
Contract No. 6 - 'D' Warehouse, Back Sheds and all export offloading to Sheds and Stacking Areas other than 'A', 'B' and 'C' Warehouses.

CUSTOMS QUAY

All Operations
Contract No. 7 – Nos. 1, 2 and 3 Berths and Quay Transit Sheds and other sheds and Back Shed operated by the Authority.

2. Tenders which must be submitted for each Contract on separate official Form of Tender provided by the Authority and returned in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL TENDER FOR SHOREHANDLING CONTRACTS, LAGOS' should be addressed to the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, Private Mail Bag 12588, 26-28, Marina, Lagos, as so to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of Friday, 15th November, 1963.

3. Official Forms of Tender and other tender documents may be collected either from the Secretary to the Authority or from the Port Manager, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt after tenderers have complied with paragraph 4 below.

4. Tenderers must first pay to the Authority's Cashier, Accounts Department, either at Apapa Quay or at Port Harcourt Quay, a deposit of £10 (ten pounds) in respect of each contract for which a tenderer wishes to tender, and present the receipt or receipts therefor to the Secretary to the Authority in Lagos or to the Port Manager in Port Harcourt for the issue of the official Form to Forms of Tender relating to such receipt or receipts.

5. Tenderers may tender for all or any number of the 7 Contracts listed in paragraph 1 above and it is hereby emphasised that tendering for any number of Contracts requires deposits of £10 each for the number of Contracts tendered for.

6. Deposit will be returned on receipt of bona fide tenders.

7. Tenders other than from Dock Labour Contractors properly registrered with the Ministry of Labour in accordance with the Dock Labour registration and Control of Employment Scheme, Lagos, will not be considered, and the Authority does not bind itself to accept the lowest or any tender.

Date: 30th October, 1963
N. P. A. Notice No. 905.

BAYO KEHINDE
Secretary To The Authority

# Oro Awon Eleha Fe Da Enia Kika Duro

KADUNA—Ọrọ 'OLOFINTITỌ' Eleti-Ọfẹ ti o mbere wipe bawo ni ao ṣe ka awọn ẹlẹha Hausa ni Oke Ọya ni oju kẹta iwe ọsẹ ti o kọja ti so awọn ọlọgbọn kọ nitoripe ọna ti awọn ni awọn fẹ fi ka awọn ẹlẹha na ti yatọ patapata, awọn kan si ni ọna na yio da ija silẹ larin awọn ara ilu Nigeria

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, nwọn ni ẹgbaji awọn akọwe alabẹwo akania ni wọn yan lati Ipinlẹ Iwọ Orun ati Ila Orun lọ si ilẹ Hausa sugbọn a gbọ wipe awọn Hausa ara Oke Ọya ko ni fun wọn laye lati ka awọn obinrin ẹlẹha wọn rara.

Nwọn ni iye ti awọn akọwe Hausa ti nwọn ba yan tele wọn lẹhin ba pe awọn obinrin na fun wọn ni wọn ni lati gba ki nwọn kọ silẹ sinu iwe.

Mo gbọ wipe awọn oṣelu Ila Orun ni Ẹnugu ti faake kọri wipe awọn ko ni gba iyẹn. Ewo ni ẹnyin Yoruba ṣe tabi ẹ o ma wo iran? ni Ni Ẹnugu tiṣe olu ilu ati Ijoko Ijọba Ipinlẹ Ila Orun, a gbọ wipe awọn alakoso Ijọba ibẹ ti ran ogunlọgọ akania ati awọn alabẹwo lọkunrin ati lobinrin lọ si ilu awọn Hausa lati lọ kania gẹgẹbi adehun ti gbogbo awọn olotu Ijọba Ipinlẹ kọkan ti ṣe wipe awọn yio jẹki awọn enia Ipinlẹ miran wa foju si enia-kika ni Ipinlẹ olukuluku, ki o ba ma si madaru ninu enia kika na.

Onirohin wa fi ye wa wipe awọn alaṣe Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ti paṣẹ fun awọn akọwe akania ati awọn ọga olubẹwo wipe ki nwọn maṣe gba gbẹẹre nibikibi ti nwọn ba gbe yan wọn si; ti nwọn ba sọ wipe awọn ẸLẸHA obinrin wa ninu ile kan ti nwọn fẹ ka, ki nwọn wọ ibẹ laifoya, ki nwọn fi oju wọn ri gbangba wipe otitọ ni iye awọn ẹlẹha ti nwọn wipe o wa nile na wa nibẹ.

Bi bale ile na ba kọ fun wọn lati ṣe bẹ ki awọn akọwe akania na yara ṣe iwe ikede lati fi ọrọ na si iwaju ọga-agba tiṣe olori awọn akania l'Eko ki tuu o fi ẹda iwe nakọkan sọwọ si Kaduna ati Ẹnugu.

"Olofintoto" Ni:

# Egbe Alakuko ( NCNC ) Di Aworerin

Ni ọsẹ ti o kọja ni mo mbere ọrọ pataki kan lọwọ ẹnyin ọmọ Yoruba nipa awọn enia ti a tun fẹ ka jake jado gbogbo ilẹ Nigeria ti mo gbọ wipe awọn kan nile Hausa ni awọn ko ni jẹ ki awọn akọwe " KAFIRI" kan wọ iru agbala awọn lati ka awọn obinrin ẸLẸHA awọn. awọn ni ọrọ na dabi nkan ti o le mu ede-aiyede lọwọ nitoripe awọn enia kan le ko ọkan mọkan ni ọna ti ko tọ.

ẸLẸHA KO DIBO

Nitotọ awọn obinrin Ijọba Ariwa ko ni di ibo lọjọ ti a ba ndibo kakiri gbogbo ilẹ Nigeria, sugbọn awọn baale wọn mọ ire ti o wa ninu a nkania ti nwọn ntẹnu mọ wipe awọn fẹ ki nwọn ka awọn iyawo awọn ni iyẹwu.

Iyẹn bẹ, ọrọ Olofintoto mi ti ọsẹ yiiori awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti a npe orukọ wọn ni ALAKUKỌ (NCNC.) ti amodi aiperi fẹ wọ ọrọ wọn kakiri gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun.

AIPERI

O to oṣu mefa nisisiyi tabi ju bẹ lọ ti rogbodiyan ti bẹ si arin awọn ọmọ ẹgbẹ oselu na ni Ipinlẹ Iwọ Orun lori wipe tani ao fi ṣe ọga tani a ko fi ṣe ọga kaka ki rogbodiyan ọrọ wọn na dinku nṣe ni o ndada si.

PẸLU AKANDUN

Bi awọn agbalagba ti o wa ninu ẹgbẹ na ti ndero ọrọ na wipe ki o ma tu sita ni gbogbo rẹ ndi nkan ti awọn ara okere nri. Bi awọn agbalagba ibẹ ti nlo egbogi AIPERI si amodi na ni arun akandun tun njade lọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ na.

Ọrọ rogbodiyan na so asọ kọ fun Olori wọn, Dokita Okpara paapo, o pare Ibadan titi ẹsẹ mọto rẹ fẹrẹ parẹ si arin ọna Warri si Ibadan.

## Isobo Winni

Gbara ti nwon da ipinlẹ agbede meji kan silẹ ni Iwo Orun ni awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko tibẹ ti pin si meji ti awọn kan ba igbi lọ, awọn kan ni ọrọ Oloye Okotie Eboh minisita alamojuto eto inawo Ijọba Apapọṣe ti awọn kan ninu awọn ilu Urhobo ko fẹ gbọ tirẹ ni o fa a; awọn gan ti awọn alagbara inu ẹgbẹ Alakukọ na ti o ṣe fiari si Alhaji Warri ni o fa iṣubu ti nwọn ṣubu nibi idibo na.

## Egbe Fara Korin

Ni ilu Ibadan, awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti da si meji lori ọrọ aṣiwaju ti nwọn yan fun wọn; awọn kan ni tori torun awọn Ọgbẹni Adeoye Adisa ni awọn yio ba lọ, awọn kan ni Ọgbẹni Akinjinde ni awọn mọ ni Olori awọn tuntun.

Ni ilu Abẹokuta, awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ tibẹ ti fara korin, nwọn ni awọn rọ awọn ogunna gbongbo meji kan ti nwọn wa ninu ẹgbẹ na loye.

(Wo yoku iwe ewe kẹjọ)




## E ka oro Ayiluka

Ibadan Lo Mo O Ko Mo Layipo

Ni oju ewe karun

# Jeki Nwon Ka E Tomo-tomo

# ELETI-OFE

( ANJU WỌN KOSE WILẸJỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosọkọ Street, Lagos, P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAM "ELETI-ỌFE" LAGOS Phone 23370

VOL XIV. NO 893 SATURDAY NOV. 3 – NOV 8, 1963


# Iwe Si Olotu

# Eleti Ofe D'araba

Oro Olotu :-

## Jẹki Nwọn Ka O Fun Ire ....

Kakiri gbogboagbaiye ni a mọ wipe ilu ti ko ba ti si efin nibẹ awọn enia ibẹ kişe. Nkan ti ni jẹki awa on we irohin Eleti–Ọfẹ sọ ọrọ yi ni nipa adehun nla kan ti gbogbo awọn olotu Ipinlẹ Ijọba wa fọwọ si n'gbakan lori atunka awọn enja ti nwọn tun fẹ ka.

Nwọn ko pe awa oniwe irohin kan sibi ipade bonkẹlẹ ti awọn Olotu wa na şe ni alẹ ọjọ kan l'Eko, şugbọn bi Awo ti olu ni Awo njo. Nkan ti a gbọ ni pataki ni ayọrisi ipade wọn na ni wipe nwọn şe eto bi awọn io ti şe yan ogunlọgọ awọn akọwe akania lokunrin ati lobinrin ti nwọn yio fi ọjọ mẹrin gbako kania ilẹ yi, ati pe nwọn yio fi awọn akania na lọ ara wọn, awọn kan lati Oke Ọya a wa si isalẹ Nigeria ni Gusu lati wa şe abẹwo bi nwọn ti nkan awọn enia ti nwọn ri ka si, ki o ba mọ si wipe a nka awọn enia ti a ko fi oju kan ninu ile rara.

Awọn Yoruba ni ọrọ agbalagba bi ko ba şẹ lowọ, a şẹ lọjọ alẹ; ẹjọwọ awa Eleti—Ọfẹ fi ODUDUWA ti o şẹ gbogbo wa bẹ ẹnyin Yoruba ki ẹ fi ọrọ ẹgbẹ oşelu silẹ, ki a panupọ ki a jẹki nwọn ri wa ka fun gbogbo ọjọ mẹrin ti nwọn fẹ fi ka gbogbo enia na fun ire ati ilọsiwaju ilẹ wa, ki a ba mọ ko abamo lẹhin ọla.

Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọlu abi, bi o ba de inu rẹ a di odidi. Ẹ jẹki nwọn ka nyin fun ire gbogbo wa.


YOUR SPECIALIST FOR ALL

BUILDING MATERIALS

**BROSSETTE**

**(NIGERIA) LTD.**

WHARF ROAD – APAPA – (NIGERIA)
P.M.B 1135 – APAPA

*At your service*

- STOCK
- SPECIAL ORDERS
- TECHNICAL INFORMATIONS


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

INVITATION TO TENDER

Contracts for the supply of Shorehandling at Port Harcourt Quay.

The Nigerian Ports Authority invites tenders from Contractors to supply with adequate supervision, experienced labour for the handling of cargo at Port Harcourt Quay in respect of the following contracts :

Contract No. 1 – Nos.1, 2 and 3 Berths
Contract No. 2 - Nos.4, 5, 6, 7 and 8 Berths.
Contract No. 3 - Arcon Sheds and 'A' Warehouse.
Contract No. 4 - All exports offloading to sheds and stacking areas other than Arcon Sheds and 'A' Warehouse.

2. Tenders which must be submitted for each Contract on a separate official Form of Tender provided by the Authority and returned in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL—TENDER FOR SHOREHANDLING CONTRACTS, PORT HARCOURT" should be addressed to the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, Private Mail Bag 12588, 26-28, Marina, Lagos, so as to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of Friday, 15th November, 1963.

3. Official Forms of Tender and other tender documents may be collected either from the Secretary to the Authority or from the Port Manager, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt after tenderers have complied with paragraph 4 below.

4. Tenderers must first pay to the Authority's Cashier, Accounts Department, either at Apapa Quay or at Port Harcourt Quay, a deposit of £10 (ten pounds) in respect of each contract for which a tenderer wishes to tender, and present the receipt or receipts therefor to the Secretary to the Authority in Lagos or to the Port Manager in Port Harcourt for the issue of the official Form or Forms of Tender relating to such receipt or receipts.

5. Tenderers may tender for all or any number of the 4 Contracts listed in paragraph 1 above and it is hereby emphasised that tendering for any number of contracts requires deposits of £10 each for the number of contracts tendered for.

6. Deposits will be returned on receipt of bona fide tenders.

7. Tenders from Contractors other than those who have had considerable experience in similar work will not be considered and the Authority does not bind itself to accept the lowest or any tender.

N. P. A. Notice No. 906.

Date: 30th October, 1963.

BAYO KEHINDE
Secretary To The Authority

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo Ayiluka

## Ibadan Lo Mo

Mo ma ngbadun awọn Yoruba ti nwọn ba wa nibi fanji, ti nwọn nyọ ọrọ apara nlanla si ara wọn bayi: 'ỌBỌ KO SI NI IDERE tabi IBADAN LO MỌ, O KO MỌ LAYIPO.' Ọrọ pọ ninu ọro apara wọn na ṣugbọn bi enia ko ba jẹ ẹaiti o gbọ ede Yoruba jinna ko ni mọ nkan ti nwọn nsọ.

## O Ko Mo Layipo

Nkan pọ nidi ọrọ ede aiyede ti o bẹ si ẹ larin ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni Ipinlẹ Iwọ Orun ati agbedo meji rẹ pelu Ipinlẹ Ila Orun. Boya nkan ti mo wi yi ko ye ẹnyin ọkawe emi Ayiluka; mo ni ede aiyede wa pẹrẹwu larin awọn ẹgbẹ Alakukọ ti o bẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun jake jado, ija ni Sapẹlẹ ati Warri bẹsi ni ija wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn wa ni Ẹnugu ati Owerri ni Ipinlẹ Ila Orun.

Ko si awọn ọmo ẹgbẹ na ni Kaduna ati Kano rara, awọn ti nwọn ba sọ wipe ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni awọn ni Oke Ọya abẹ ile wọn ni nwọn ti nsọ ọ. ẸGBẸ ALAKUKỌ ko ri senge da lọdọ awọn RANKA DEDE nibikibi ni Ipinlẹ Ariwa.

## Buroda Alagbara

Emi Ayiluka ti mọ ilu Ibadan ni ilu awọn alagbara ti pẹ; mo ti ngburo awọn alagbara, awọn bi balẹ Olugbode, balẹ Ogunmọla, balẹ Oke Fọkọ pẹlu awọn jagunjagun ilu Ibadan atijọ ki ọrọ to wa kan awọn ọdọmọdekunrin ode isisiyi.

Alagbara ni awọn ọdọ oṣelu mọ Ologbe Adelabu Adegoke "PẸNKẸLẸMẸSI" si, mo si ngbo irohin bokẹlẹ kan wipe Ọgbẹni Fani-Kayọde paapa nfẹ joye Alagbara nilu Ibadan. Boya Ọgbẹni Fani-Kayọde a fẹ gbọ imọran mi, imọran na niyi: Oye Alagbara ṣoro jẹ lọdọ awọn ara Ibadan nile ati loko nitoripe Ibadan ni ẹ mọ, ẹ ko mọ Layipo, bẹ Layipo si ni baba Ibadan.

## Abiola Oṣhodi

Ajalu nla kan jalu awọn ẹbi Oshodi ati ẹbi awọn Dokita Ajibade ni Eko ni arin ọsẹ yi nipa iku gbajumọ kan ninu awọn ọmọbinrin wọn ẹniti nwọn npe ni Abiọla Oshodi (Alarede Anderson-Duyile) ti o jalasi ni ọjọ Aiku (Sunday) ti o kọja yi. Ẹni ọdun mejidiladọta ni arabinrin na, akọbi ọmọ ologbe na ni Omidan Peju Oni-Orisan ti o nṣiṣẹ ni ọdọ awọn oniṣẹ aropileni.

Ọmọ bibi inu Iya alagba Dorcas Ajunti gbogbo ara Eko mọ adape orukọ rẹ ni Rali Oyinbo ni ologbe na, o si jẹ ọmọ-ẹgbọn Dokita Ajibade ti o wa ni Port-Harcourt.

Nigba aiye rẹ, Ologbe na jẹ okan ninu awọn ọmọge ilu Eko ti o gbafẹ pupọ. ABIỌLA AKANKẸ AGAN, ỌMỌ ỌYA, Ọrun re o!

## Ayekoto

Mo gbọ ọrọ kan fẹre ninu ọsẹ ti o kọja wipe ọrẹ mi, Ọgbẹni Victor 'Bisi Ọnabanjọ, ẹniti gbogbo awọn ara ilu Nigeria mọ adape orukọ ni AIYEKOTO fẹ fi iṣẹ onirohin silẹ laipẹ yi. Ọrọ na ko ti ye mi si, mo si ti wa Ọgbẹni Ọnabanjọ na lọ lati gbọ tẹnu rẹ, nko ba nile, boya o lọ si Ijebu Ode nitoripe ỌMỌ ỌBA-N'TA nile emi Ayiluka mọọ bi ẹniti o n'owo.

"Aiyekoto" fi igba kan se ọga mi nibi iṣẹ, mo mọ owo rẹ, on na si mọ ọwọ mi daradara. Gegefalari ikọwe rẹ kiṣe kekere. Awọn oṣiṣẹ Loko ni ọgba teluwe mọ ni Ebute-Mẹtta ati ni Ẹnugun. Awọn oṣiṣẹ ọkọ oju-irin ti a npe ni MARINE WORKERS ni atijọ ko ni gbagbe ija wọn ti tenu pẹlu Ọgbẹni 'Aiyekoto' jọ gba la. A ja fun wọn titi, nwọn fi owo kun iṣẹ wọn. Ewo ni mo le gbagbe nibẹ, ojọ ti Oyinbo ọgba Loko kan fẹ gba mi lẹ nitoripe mo nse ọtẹlẹmuyẹ lati gooro won ni tabi lọjọ ti emi Ayiluka paapa ba awọn oṣiṣẹ da iṣẹ ilẹ lọ si ori koriko ni Oko-Awo l'Eko?



'Bisi Ọnabanjọ

Mo niran wipe mo kọ iwe asọtẹ kan wipe ẸGUN IJỌBA yio gun ọpọlọpọ awọn oṣiṣẹ Ijọba ti nwọn da iṣẹ silẹ ni na lẹṣẹ. Nitoto ẸGUN IJỌBA gun wọn lẹṣẹ, nwọn si da ọpọlọpọ duro lẹun iṣẹ oojọ wọn. Lati ọjọ na ni Ọgbẹni 'Aiyekoto' ati awọn miran ti a jọ nṣe iṣẹ akọwe onirohin kiri ti npe emi Ayiluka ni "ẸGUN IJỌBA", bẹ ko si ẹniti ko le gun afi ẹniti o ba mọ iwọn ara rẹ. Ijọba Oyinbo ko mọ olowo afi awọn ẹniti ti nwọn ba joko jẹjẹ

## Aso Bosikona

Emi Ayiluka pade diẹ ninu awọn ọga Ibo ti nwọn nta aṣọ BOSIKONA, ti nwọn wa ni Eko

(Wo yoku loju ewe kejo)


CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT:

IKORODU TRADING COMPANY
27 & 28, Balogun Street, Lagos.

# NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED

## Balance Sheet as at 30th June, 1963

| 1962 £ | | £ | £ |
|---|---|---|---|
| | Capital | | |
| | Authorised: 3,250,000 Ordinary Shares of £1 each | 3,250,000 | |
| 3,180,539 | Issued: 3,182,452 Shares | 3,182,452 | |
| | Less:-Calls in Arrear | 1,913 | 3,180,539 |
| 170,000 | Reserve Fund | | – |
| 3,067 | Profit and Loss Account | | – |
| 3,353,606 | | | 3,180,539 |
| 30,000 | Future Income Tax | | – |
| 5,921,175 | Current, Deposit and Other Accounts | | 3,813,935 |
| — | Loans and Advances from Other Creditors | | 1,000,000 |
| 606,756 | Acceptance, Endorsements and Other Engagements on behalf of Customers per contra | | 660,400 |
| £9,911,537 | | | £8,654,874 |

Notes:

(i) All Reserves and Provisions carried forward from previous years have been utilised in writing off Bad Debts.

(ii) Payment of Dividends on the Issued Shares of the Bank will be suspended until such time as, in the opinion of the Board of Directors, adequate provision for Doubtful Loans and Advances has been made.

F. O. AWOSIKA, Chairman
S. L. DUROSARO, Managing Director
A. A. O. DUROSHOLA, Director

| 1962 £ | | £ | £ |
|---|---|---|---|
| 403,705 | Cash on Hand and Balances with the Central Bank of Nigeria | | 364,808 |
| 155,509 | Balances with, and Cheque in course of Collection on other Banks | | 259,311 |
| 70,000 | Money at Call and Short Notice | | 430,000 |
| 500,000 | British and Nigerian Government Treasury Bills | | 150,000 |
| | Investments at Cost:- | | |
| 115,420 | Nigerian Government Securities | – | |
| 178,990 | British Government Securities (Market Value £34,002) | 29,002 | |
| 423,692 | Others (including Subsidiary Companies) | 109,9[illegible] | 138,982 |
| 6,567,274 | Loans and Advances to Customers and Other Accounts (including Subsidiary Companies), less Bad Debts written off | | 5,670,922 |
| 890,191 | Bank Premises, Fixtures and Motor Vehicles at Cost less Depreciation | | 980,451 |
| 606,756 | Liabilities of Customers for Acceptances, Endorsements and other Engagements per contra | | 660,400 |
| £9,911,537 | | | £8,654,874 |

A. O. OSHINIBI, Director
A. A. LADEINDE, Director
F. O. SOGUNRO, Chief Accountant

## AUDITORS' REPORT

We have obtained all the information and explanations which to the best of our knowledge and belief were necessary for the purpose of our audit. In our opinion, proper books of account have been kept by the Bank so far as appears from our examination of those books, and proper returns adequate for the purpose of our audit have been received from the Branches. We have examined the above Balance Sheet which is in agreement with the books of account and Returns of the Bank. In our opinion and to the best of our information and according to the explanations given us, the said Balance Sheet is properly drawn up so as to exhibit a true and correct view of the State of the affairs of the Bank at the 30th June, 1963.

OLATUNDE AYOOLA & CO.
Chartered Accountants
THOMAS, SILVA, DAWODU & CO.
Certified Accountants
AUDITORS

Dated at Lagos this 8th day of October, 1963

## PROFIT AND LOSS ACCOUNT FOR THE YEAR ENDED 30th JUNE, 1963

| 1962 £ | | £ |
|---|---|---|
| 112,000 | Tranfer towards provision for Doubtful Accounts | – |
| — | Bad Debts written off | 1,240,877 |
| — | Losses and other charges written off | 76,618 |
| 3,067 | Balance unappropriated-30th June, 1963 | — |
| £115,067 | | £1,317,495 |

| 1962 £ | | £ |
|---|---|---|
| 112,955 | Net Profit for the year | £872,129 |
| — | General Reserves & Provisions brought forward from previous years | 442,299 |
| 2,112 | Balance unappropriated-30th June, 1962 | 3,067 |
| £115,067 | | £1,317,495 |

## To Save Food:

# Inflatable Warehouse For Tropical Countries

LONDON — A new method of storing tropical crops has been developed by British scientists which should help to reduce the tremendous losses suffered from insect damage to stored food, particularly in tropical countries.

The new method, developed over the past two years by Britain's Tropical Stored Products Centre in collaboration with commercial organisations, is an air-tight, portable, inflatable warehouse.

One will shortly be proving its worth in Africa, where it has been bought by Kenya's Maize Marketing Board to store bagged grain.

The first such warehouse to be built was demonstrated in Britain last week. It is an oval 66ft in diameter and 22 feet high and holds 500 tons of grain.

Made from nylon covered with polyvinylchloride (P.V.C.), the lack of oxygen in it kills the insects and the growth of fungi is prevented.

It is claimed that the new method saves the cost of fumigating stored grain and obviates the use of insecticides with their risk to human health.

The plastic covering is resistant to rodents and can be protected agains termites.

---

## Low-Rental Rooms For Students Going To Britain

LONDON—Thirty students from overseas are now living in lowrental private rooms at a hostel specially constructed for them in Bristol (wes ern England).

The hostel, Meridian House, was opened last weekend by Martin McLaren, Member of Parliament for north-west Bristol.

The idia of Merdian House was born in 1963 when two Brissol University students decided to do something which would ensure that overseas students had a warm welcome in Bristol.

They appealed for funds and one year later the Bristol Diocesan Board of Finance decided to assist. Later they were helped by the British Government scheme for overseas students' welfare expansion and also by the British Council.

Meridian House cost £40,000 to build.

## Helicopter Takes Buck Safety

KENYA—Sixty rare hunter antelopes, threatened with total extinction, are being flown by British Royal Navy helicopters to the safety of a game reserve in Kenya. The helicopters are from the aircraft carrier, ARK ROYAL.

The Navy was called in by the Kenya Game Department to help save the antelopes. There are believed to be only one thousand left, and they are nearly all concentrated in a small area on, the Tana River. To ensure that they do not become completely extinct, a breeding herd of them is being transferred to the 8,000 square mile National Park at Tsavo, 160 miles from Nairobi.

## Nigerian Leads British Youth Club

LIVERPOOL—A new £10,000 headquarters for the multi-racial Stanley House Youth Club whose youth leader is a Nigerian was opened in Liverpool recently.

Twenty-nine-year-old Anthony Akomah, the youth leader, is a social science graduate from Asa, and Lagos. The Club, formed a year ago, has one hundred members aged fourteen to twenty-one, three quarters of them the sons and daughters of Nigerians Ghananians, Liberians, Rhodesians, West Indians, Somalis and Indian immigrants to the city.

"Our club is different from others in Britain in that we set out to cater for the needs of members of the overseas community in Liverpool," Mr. Akomah told our correspondent. "But it is a multi-racial youth club and more members are English," he added. "One of our principal aims is to provide a centre where the youth of the area can find good recreational facilities and at the same time have an opportunity of learning a craft which would help them when they become adults," Mr. Akomah explaind.

## Lagos UPP Members Support Waddel

According to the news reaching our office Officers and committe Members of the United People's Party in Lagos have issued a statement disassociating themselves from the report which appeared in the Daily Times this week about the alledged removal of Mr. Waddell as Chairman of the Party in Lagos.

Members hereby affirmed their support and implicit confidence in Mr. Waddell. No complaint has been brought by any section of the Party in Lagos and Mainland agaist him the report thus published was unautorised.

The Party's tatement was signed by the General Secretary, Mr. Taju Thompson.

**Plushes, Velvet Velveteen, Damask & Building Materi ls**

PLEASE CONSULT US

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, (Fa... Market)
LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

## Ayiluka Ni

# Aso Bosikona

(O bere loju ewe keran)

Lati wa foju kan Onimi-Ejo Oloye Festus Okotie Eboh, minisita alamojuto eto inawo Ijoba Apapose ti awon onisowo ara Aba wa ba wipe ki o gba awon lowo aja-ga owo-bode (customs duties) goboyi ti Ijoba fe di mo awon leru lori aso bosikona ti awon nko wolu ti Ijoba nfe ba owo le.

### Ija Pari

Mo gbo wipe Ijoba ti gbo ti awon enisowo aso bosikona na, awon si ti jogunu, awon ti din owo-bode ti nwon nja si lori na; mo ro wipe eyi ni awon omo EGBE ALAKUKO agbegbe ilu Ibo yio fi pari ijaa be'le ti o wa isrin won. Dokita Okpara gbon, awon omo ehin re paapa si gboju

Nipa oro ija ti awon egbe Alakuko ni Ibadan, mo gbo wipe awon Ogbeni T. O. S. Benson ati F. S. McEwen, awon olori egbe na l'Eko ti bo sokoto won lati da si oro na. Boye Ogbeni R O Akinjide a ju ipo olori egbe na sile fun Ogbeni Adeoye Adisa. Olorun ki o fun won se sugbon tawo ni nwon ti fe se oro awon omo egbe Alakuko ilu Ebo si?

Mo fi eri Akuko be gbogbo eniyin omo egbe, e fi oro iia sile na, ki e jeki awon ka gbogbo wa ile no taya ni ile awa Yoruba.

### Jaja Keran

Iyen be, Ogbeni Jaja Wachuku, minister alamojuto Ijoba okere keran asumegun lodo awon ara ilu wa fun oro aba ti o da nibi apejo awon Ijoba agbaiye lori awon enia-dudu isale ilu Afirika ti awon alawo funfun kan nfi iya je won. Emi Ayiluka gbo wipe gbogbo awon omo ile igbimo abolotu jiroro ti se ikile fun Ogbeni Wachuku wipe ki o fowo owo ro bo ase nitoripe iso ti awon ko ran ni o nje nile ajoji.



Ogbeni Jaja Wachuku

## Adegbenro Gba Owo Irin-Ese

( O bere loju ewe keji )

owo irin-ese na de kotu nla, Oloye Oladipo Moore tise agbejoro Oloye Akintola tako o; awon adajo ti o joko lati gbejo na ni ki awon mejeji lo sile won lati lo pari re.

Awon adajo na si da igba fun won lati wa so bi awon ba ti pari oro owo irin ese na si. Ni ose yi ni nwon to pase si i wipe ki Oloye Akintola lo san ogota dinlegbefa ponun pelu sile mejo ati kobo meta (£1,140.8.3d fun Adegbenro. Adajo Adetokunbo Ademola tun pase wipe ki ile ejo giga Ipinle Iwo-Orun ni Ibadan ri si i pe Oloye Akintola san gbogbo owo irin-ese na.

## Ogun Besile Nilu Dahomi

(O bere loju ewe kinni)

Eleyi mu ki awon Ibariba ti se ara ilu Ogbeni Maga lati ilu oke Dahomi binu, nwon fi ake kori wipe dandan awon ni lati ri Maga laye, bi awon ko ba ri i oku ni lati sun. Nitoto enia meji ni nwon fi ofa won pa lojo na, eleyi wa mu ki awon soja paapa yinbon fun awon Ibariba ti nwon wipe afori afese, awon ni lati foju kan ara ilu awon. Ogbeni Maga, enia merin ni ibon awon soja pa ni apafon lojo na, sugbon ni ana a gbo wipe gbogbo awon ti nwon pa lori rogbodiyan na ti di medogbon


**Available!**

Choose your Mercedes-Benz 220s NOW.

A rich variety of colours is at last available.




**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, (EB) IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCOURT, ABA.

Sub-Distributors:

**ARMELS TRANSPORT LTD.**

BENIN CITY, ONITSHA, ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street. Phone 23370 Lagos; Editor: 'Olotu' Ola Onatade, Kosoko Street, Box 457, Lagos.